# ẸBẸ̀ MOSE FUN IFARAHÀN ỌLỌRUN
## Ẹksodu 33:1-23
## ẸKỌ 68 FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Iwọ o pa a mọ li alafia pípé, ọkàn ẹniti o sinmi le ọ" (Isaiah 26:3).**

### Lai ni Ọlọrun, Wọn jẹ Alailagbara

Nigba ti ogunlọgọ awọn Ọmọ Israẹli bẹrẹ irin-ajo wọn lọ si Ilẹ Ileri, wọn ko mọna. Wọn ko mọ ibi ti wọn o ti ri ounjẹ fun ara wọn ati agbo ẹran wọn, tabi ibi ti omi wà lati mu. Lai ni Ọlọrun lati dari wọn, wọn i ba ti ṣegbe lẹṣẹkẹṣẹ ninu aginju.

Lati ibẹrẹ irin-ajo wọn Ọlọrun ti n lọ ṣaaju wọn ninu ọwọ̀n awọsanma ni ọsan ati ninu ọwọ̀n ina ni oru. Wọn mọ pe Ọlọrun wà nibẹ, nitori O ti bá Mose sọrọ lati inu awọsanma naa wa, gbogbo wọn si ti ri ogo Rẹ̀ (Ẹksodu 16:10-12).

### Ogo Ọlọrun lori Oke

Ọwọ̀n náà ti ṣe amọna wọn titi de Oke Sinai, nibi ti awọn Ọmọ Israẹli duro fun igba diẹ. Nibẹ ni Ọlọrun ti fi ara hàn ninu ọla nla ati agbara Rẹ̀, laaarin aara ati manamana ati isẹlẹ; ipe Ọlọrun si dún kikankikan pẹ́ titi, O si pe awọn eniyan naa sunmọ tosi oke naa lati gbọ́ ofin mimọ́ Rẹ̀. Wọn ti gbọ ohùn Rẹ̀, Ọrọ ti O sọ si ti ye wọn; sibẹ laaarin ogoji ọjọ, wọn ti rọ ẹgbọrọ maluu wura fun ara wọn lati fi dipo Ọlọrun Ọrun Atobijulọ. Dajudaju Ọlọrun jare lati fẹ pa iru awọn eniyan abọriṣa ati alaimoore bayii run. Ro ti aanu Rẹ̀ nla ni dida wọn si, ni idahun si awọn adura Mose!

### Ọlọrun Kọ Awọn Eniyan Rẹ̀

Nigba ti Ọlọrun sọ fun Mose lori oke naa pe, Israẹli ti dẹṣẹ, O wi pe: "Lọ, sọkalẹ lọ, nitoriti awọn enia rẹ, ti iwọ mú gòke lati ilẹ Egipti wá, nwọn ti ṣẹ̀" (Ẹksodu 32:7). Ọlọrun ko ni gba awọn ẹlẹṣẹ wọnni si eniyan Rẹ̀, nigba ti O si n ba Mose sọrọ nipa wọn, O pe wọn ni "awọn **enia** rẹ."

A ko le jẹ ọmọ Ọlọrun bi a ba ni ẹ̀ṣẹ ninu igbesi aye wa. Nigba ti a **ba jẹwọ** ẹṣẹ wa ti a si ronupiwada, ti a si ri idariji Jesu gba, nipa bayii a bí wa sinu ẹbi Ọlọrun; ṣugbọn bi a ba tun dẹṣẹ, a ki tun i ṣe ọmọ Rẹ̀ mọ́. Jesu sọ fun awọn Ju nigba ti wọn dẹṣẹ pe eṣu ni baba wọn (Johannu 8:44). Ọlọrun dari Johannu lati kọwe pe: "Ninu eyi li awọn ọmọ Ọlọrun nfarahan, ati awọn ọmọ Èṣu: ẹnikẹni ti kò ba nṣe ododo kì iṣe ti Ọlọrun, ati ẹniti kò fẹràn arakunrin rẹ̀" (1 Johannu 3:10). A ri i pe nnkan ti a tilẹ le pe ni ẹ̀ṣẹ kékèké bi ṣiṣai fẹran arakunrin wa, yoo yà wá nipá kuro ninu ẹbi Ọlọrun, yoo si sọ wa di ọmọ Satani.

### A Gbé Agọ kuro ni Ibudo

Ọlọrun ṣaanu fun Israẹli nigba ti wọn ronupiwada, ko si run wọn patapata; ṣugbọn O sọ pe Oun ko le gbe laaarin awọn olori kunkun eniyan bẹẹ. Mose ni àgọ́ kan nibi ti oun i ti i maa pade Ọlọrun ti i si maa jọsin, eyi ti o gbé lọ si okeere réré si ibudo nisisiyii. O pe e ni Agọ Ajọ. Nibẹ ni Mose ti lọ bẹbẹ fun awọn eniyan naa, nibẹ ni Ọlọrun si ti ba a sọrọ ninu ọwọ̀n awọsanma. Ẹnikẹni ninu awọn Ọmọ Israẹli ti o ba fẹ lati sin Ọlọrun ni anfaani wà fun lati ba a lọ. Nigba ti awọn eniyan ti o duro ninu àgọ́ wọn ri i ti ọwọ̀n naa sọkalẹ sori agọ naa, gẹgẹ bi apẹẹrẹ ipadawa oju rere Ọlọrun, wọn dide duro lati jọsin.

### Ọlọrun ṣe Ileri lati fi Angẹli kan ṣe Amọna wọn

Ọlọrun ti ṣaanu fun Israẹli; ṣugbọn O mọ pe o ṣe e ṣe fun wọn lati tun ṣẹ̀, boya nigba naa Oun ko ni ṣanu fun wọn mọ́, wọn o si ṣegbe patapata. Nitori idi eyi O wi pe Oun yoo rán angẹli kan lati maa ṣaaju wọn, nitori Oun funra Rẹ̀ ko ni ba wọn gbe.

A o kọ́ nigbooṣe pe nigba kan ti awọn Ọmọ Israẹli dẹṣẹ, Ọlọrun rán ejo oloro saarin wọn lati bù wọ́n ṣán, ẹnikẹni ti wọn si bujẹ kú. Ni akoko miiran iná jade lati ọdọ Oluwa si ibudo o si jó ọpọlọpọ eniyan run nitori ẹ̀ṣẹ wọn (Numeri 11).

### Ẹbẹ Mose

Ọkàn Mose gbọgbẹ lori ironu pe Ọlorun kò ni ba wọn lọ. Mose kò tilẹ ro rárá pe oun le mu orilẹ-ede nla naa de Ilẹ Ileri lai jẹ pe Ọlọrun wa ni tosi rẹ timọtimọ lati ran an lọwọ. Lakọkọ ni Egipti nigba ti Mose ni ifẹ lati ran awọn eniyan rẹ lọwọ, o gbiyanju ninu ipá rẹ lati jẹ iranwọ, ṣugbọn o ri i pe oun ti ṣe ohun ti kò tọna. Nigba ti oun ti gbiyanju lati ṣe ilaja laaarin awọn ọmọ Heberu meji, wọn kigbe pe "Tali o fi ọ jẹ olori ati onidajọ lori wa?" Mose ti kẹkọọ pe oun kò le ṣe nnkan kan lai si iranwọ Ọlọrun, nitori bẹẹ o beere fun ifarahan Ọlọrun lati maa ba oun lọ, lai jẹ bẹẹ oun ko ni daba lati mu awọn eniyan naa tẹsiwaju rárá.

**A n fẹ́ Ifarahan Ọlọrun**

Awọn miiran ti wọn ṣẹṣẹ di Onigbagbọ a maa sinmi le Oluwa patapata ni ibẹrẹ, ṣugbọn lẹyin igba diẹ wọn a rò pe awọn le dá nikan maa lọ lailewu. Wọn kò ni gbadura to igba ti wọn ṣẹṣẹ ri igbala, wọn ko si ni fi akoko pupọ ka Bibeli ti Ọlọrun fi ṣe amọna fun igbesi-ayé Onigbagbọ. Diẹ diẹ ni wọn n ṣako kuro lọdọ Ọlọrun. Nigba ti wahala ba si de ba wọn, lojiji wọn a ri i pe gedegbe ni wọn dá duro, wọn a si ri i pe awọn ni lati ni iranwọ Ọlọrun lọnakọna -- ṣugbọn O jinna réré. Mose kò fẹ ba ara rẹ ninu ahamọ nigba ti o ṣe pe Ọlọrun rẹ wà lokeere rere. O wi pe "Bi oju rẹ kò ba bá wa lọ, máṣe mú wa gòke lati ihin lọ."

Eyi ni o ni lati jẹ ipinnu olukuluku Onigbagbọ. A kò gbọdọ lọ si ibikibi ti a kò le mu Oluwa lọ pẹlu wa; a kò gbọdọ sọ ohunkohun ti a ko fẹ ki O gbọ́. A ni lati ka Ọrọ Ọlọrun ki a si gbadura si Jesu to bẹẹ ti a o maa fi ri ifarahan Rẹ nigba gbogbo lẹgbẹ wa timọtimọ.

Mose ba Ọlọrun sọ asọye: Bawo ni awọn orilẹ-ede ajeji yoo ṣe mọ̀ pe eniyan Ọlọrun ni awọn wọnyii i ṣe bi oju Rẹ ko ba ba wọn lọ? Bawo ni awọn eniyan lonii ṣe n mọ̀ awọn ẹni ti i ṣe ọmọ Ọlọrun? Wọn le mọ awọn ọmọ Ọlọrun tootọ nipa Ẹmi Ọlọrun ti n ba wọn gbé. Ijọ kan le pejọ lorukọ Jesu, ṣugbọn bi ẹ̀ṣẹ ba wà ninu ọkàn wọn Ẹmi Ọlọrun kò ni wà pẹlu wọn. Ijọsin wọn jẹ omulẹ-mofo lasan. Ẹni ti ko gba pe Ọlọrun wa le maa wo iru awọn eniyan bẹẹ ki o si wi pe igbesi aye ti oun ko yatọ si ti wọn.

**Ibi ti Ẹmi N Gbé**

Bawo ni eyi ti yatọ to si ijọ ti Ẹmi Ọlọrun n ba gbe! Ifẹ ati irẹpọ wà laaarin awọn ará, nitori Ẹjẹ Jesu ti ṣe wọn ni ọ̀kan; agbara wà lati gba adura igbagbọ eyi ti yoo wo alaisan sàn; Ẹmi Mimọ si n sọrọ idalẹbi sinu ẹlẹṣẹ ti n fẹ otitọ; Oun a si mú ki o fẹ lati ri igbala. Ọlọrun wà nibẹ! A le mọ ifarahan Rẹ̀ ti o ni ọ̀wọ̀. Awọn orin iyin ni imisi, wọn n ti inu ọkàn ti ó mọ Ọlọrun jade wá. A rán Ọrọ Ọlọrun jade ni ọna ti n fi ẹ̀ṣẹ hàn, ti o si n kọ́ awọn eniyan ni ọna si Ọrun. Iṣẹ ami ti Bibeli a si maa tẹle awọn ti o ba gbagbọ (Marku 16:17, 18).

O ti ṣe danindanin to lati ni oju Ọlọrun pẹlu wa! Ẹmi Rẹ̀ a maa gbe ninu awọn ọmọ Rẹ̀ ti a tun bi; nigba ti wọn ba si ri isọdimimọ, Ẹmi naa a pọ nibẹ si i; nigba ti wọn ba si ni ifiwọni Ẹmi Mimọ, igbesi aye wọn a kun akunwọ silẹ pẹlu ororo ayọ̀ nì, iná ifẹ Rẹ̀. Wọn a gba agbara pẹlu Ẹmi Mimọ́ naa lati ṣiṣẹ ti yoo mu eso wá fun Oluwa. Ẹmi yii a maa ba wa gbe niwọn igba ti a ba n tẹsiwaju lati maa wà fun Ọlọrun, ti a si n ba Oluwa sọrọ lojoojumọ.

**Imọlẹ Ayé**

Ayé n ṣokunkun siwaju si i nitori ẹ̀ṣẹ awọn eniyan. Jesu ni Imọlẹ rẹ̀ kan ṣoṣo. Bayii ni Ẹmi ti o wà ninu awọn ọmọ Rẹ̀, awọn ẹni ti i ṣe fitila ninu eyi ti imọlẹ n tan, ni imọlẹ ti n dari awọn eniyan wa sọdọ Olugbala. Nitori idi eyi ni o fi ṣe danindanin pe ki a ni Ẹmi Ọlọrun ninu wa tó iwọn ti a le ri gba ki a ba le maa tan imọlẹ si ọna awọn eniyan ẹlẹṣẹ, ki wọn ba le ri ọna ti o lọ si ile Ogo.

**Mose Gba Agbayọri Adura**

Ọlọrun dahun adura Mose O si gbà lati ba wọn lọ. Mose wá beere fun awọn ibukun ti o tilẹ tobi ju bẹẹ lọ: o fẹ lati ri ogo Ọlọrun. Ṣugbọn kò si ẹni ti o le ri oju Ọlọrụn ki o si wà laaye ninu ara kiku yii. O fi Mose pamọ sinu palapala apata o si fi ọwọ Rẹ̀ bo o. Nigba naa ni O rekọja O si jẹ ki Mose ri akẹyinsi Rẹ̀ nikan. Ọkàn Onigbagbọ tootọ a maa poungbẹ lati ri Jesu; awa si n yọ̀ ninu iwọn ogo Rẹ̀ ti Oun n jẹ ki a wò. Nigba ti a ba de Ọrun a o ri I bi Oun ti ri. "Olufẹ, ọmọ Ọlọrun li awa iṣe nisisiyi, a kò si ti ifihàn bi awa ó ti ri: awa mọ pe, nigbati a bá fihàn a ó dabi rẹ̀; nitori awa o ri i ani bi oun ti ri" (1 Johannu 3:2).

## AWỌN IBEERE

1. Ta ni mu awọn Ọmọ Israẹli jade kuro lati Egipti lọ si Sinai? Bawo?
2. Ki ni ṣe ti Ọlọrun fi kọ̀ lati pe awọn Ọmọ Israẹli ni ọmọ Rẹ̀?
3. Nigba wo ni a jẹ ọmọ Ọlọrun?
4. Bawo ni awọn orilẹ-ede ajeji ṣe le mọ̀ pe Israẹli jẹ ayanfẹ Ọlọrun?
5. Bawo ni awọn eniyan ṣe n mọ pe ọmọ Ọlọrun ni a jẹ́?